# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kẹfà, Ọdún 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KẸFA, ỌDÚN 2024**
**ITUSILẸ TO JINLẸ (APÁ KẸTA)**
**AWỌN ORIN IBẸẸRẸ**

1. **Ẹ̀nyin olùkórè nín’oko!**

T’árẹ̀ fẹ́rẹ̀ mú tán;
Ẹ rọ́jú dúró de Olúwa,
Y’Ó s’agbára dọ̀tun.

Àwọn tó dúró d’Olúwa
Y’ó s’agbára wọn d’ọ̀tun,
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò,
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò bí ìdì,
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀;
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n;
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀;
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n;
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀,
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n.

2. Nígbà àrẹ́ àt’irẹ̀wẹ̀sí,

À ngb’ọkàn wa sí Ọ;
Lẹ́yìn t’agba Olùgbàlá gbọ́,
Kí l’a ó tún bẹ̀rù?

3. Ẹ yọ̀! Ó mbá wa gbé lọ́jọjọ́,

Àní títí d’ópin!
Wòkè! ẹ sì ma tẹ̀sìwájú

Y’ó fùn nyín l’ágbára!

1. **Ẹ dide, ọmọ ìgbàlà**

Ẹ̀yin t’ẹ fẹ́ Olúwa;
Dìde, ìlú alágbára
Kí ọ̀tá tó dé Síòn.

F’agbára rẹ kọrin kíkan,
Bí ìró omi òkun;
Nípa ẹ̀jẹ̀ Krístì Jésù
Àwa ju aṣẹ́gun lọ,
Àwa ju aṣẹ́gun lọ,
Àwa ju aṣẹ́gun lọ;
Nípa ẹ̀jẹ̀ Krístì Jésù
Àwa ju aṣẹ́gun lọ.

2. Ẹgbẹ́ mímọ́ ti ìgbanì

Tí wọ́n ti nrin ọ̀nà yí;
W’àsíá wọn t’ó nfẹ́ lẹ́lẹ̀
A ṣẹ́gun nípa Krístì.

3. A ti gbé ‘kú mì ní ‘ṣẹ́gun,

Ìyè wa mbẹ n’nú Krístì;
L’ọ́jọ́ ‘farahàn Olúwa
A ó hó ìhó ayọ́.

4. Láìpẹ́ aó dé’bi ìtẹ́ Rẹ̀,

A ó sì mọ Ọba Ògo,

Níbẹ̀ aó kè, Kábíyèsí”
Gbogbo wa y’ó gba èrè.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Mo pàṣẹ lónìí wí pé, ayọ̀ àwọn aninilára lórí ayé mi yóò di ibànújẹ́, ní orúkọ Jésù.
2. Ìkórajọpọ̀ àwọn àgbà ìkà tó lòdì sí ayànmọ́ mi yóò wólulẹ̀ lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti dènà ìfarahàn àwọn àlá àti ìran rere mi, kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti mú ìlọ́ra bá ìlọsíwájú mi, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, nínú ètò yìí lónìí, ìwọ yóò kú, èmi kò sìní rí ọ mọ́, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìpinnu tó lòdì sí ayànmọ́ mi yóò kú nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára òkùnkùn tí sátánì fi òróró yàn láti jẹ́ kí n dìde, kí n tún ṣubú padà, òní lo rí ayé mọ, kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára òkùnkùn ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn láti dá àlàjá mi dúró, ìwọ yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**Isaiah 40:29:** O nfi agbara fun alarẹ; o si fi agbara kun awọn ti ko ni ipa.

**Filippi 4:19:** Ṣugbọn Ọlọrun mi yoo pese ni kikun fun gbogbo aini nyin, gẹgẹ bi ọrọ Rẹ ninu ogo ninu Kristi Jesu.

**Orin Dafidi 107:20:** O ran ọrọ Rẹ, O si mu wọn lara da, O si gba wọn kuro ninu iparun wọn.

**Orin Dafidi 147:3:** O mu awọn onirora aya lara da: O di ọgbẹ wọn.

**Isaiah 57:18-19:** Mo ti ri ọna rẹ, emi o si mu u li ara da: emi o si tọ ọ pẹlu, emi o si mu itunu pada fun u wa, ati fun awọn aṣọfọ rẹ. Emi li o da eṣo ete; Alafia, alafia fun ẹniti o jina rere, ati fun ẹniti o wa nitosi, ni Oluwa wi; emi o si mu u li ara da.

**Romu 8:37:** Ṣugbọn ninu gbogbo nkan wọnyi awa ju ẹniti o ṣẹgun lọ nipa ẹniti o fẹ wa.

**Máttéù 9:21** Nítorí ó wí nínú ara rẹ̀ pé, Bí mo bá sà lè fi ọwọ́ kan aṣọ rẹ, ara mi ó dà.
**Deutérónómì 7:15:** OLÚWA yóò sì gba àrùn gbogbo kúrò lọ́dọ̀ rẹ. Kì yóò sì fi ọ̀kan nínú àrùn búburú Égíptì, tí ìwọ mọ̀, sí ọ lára, ṣùgbọ́n òn o fí wọ́n lé ara gbogbo àwọn tí ó kórira rẹ.

**Isàíàh 58:8:** Nígbàná ni ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jáde bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ jọ.

**Jeremíàh 17:14:** Wò mí sàn, Olúwa, èmi ó sì sàn; gbà mí là, èmi ó sì là; nítorí Ìwọ ni ìyìn mi.

# <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá, jẹ́ kí a mú àánú Ọlọ́run kúrò lórí gbogbo ọ̀tá ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
4. Bàbá mi, jẹ́ kí ohun gbogbo tí ó ti ṣiṣẹ́ fún àwọn ọ̀tá mi rí bẹ̀rẹ̀ siní ṣiṣẹ́ lòdì sí wọn, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ọ̀tá ayànmọ́ mi tí ó kọ̀ láti ronúpìwàdà, kí òòrùn pa ọ́ ní ọ̀sán àti òṣùpá ní òru, ní orúkọ Jésù.
6. Èmi yóò ma gbé nínú Ihò Ọwọ́ Ọlọ́run títí láí, ní orúkọ Jésù.
7. Iṣẹ́ àjẹ́ ìyówù lábẹ́ omikómi, tí ó lòdì sí ayànmọ́ mi, gba ìdájọ́ iná, ní orúkọ Jésù.